**INSTITUT DES DROITS DE L'HOMME ET DE PROMOTION DE LA DEMOCRATIE**

**LA DEMOCRATIE AU QUOTIDIEN**

Siège : CODIAM à COTONOU (Bénin)
BP : 08-1120 COTONOU
Tél. : (229) 30-27-06 – Fax : (229) 30-27-07

# L'EDUCATION DES POPULATIONS EN MATIERE DE VOTE

## 3

Version Yòrùbá

*Eré akɔ́nilɔ́gbɔ́n kpɛlu ɛ̀rɔ amóhùnmáwòrán lori*

**EKƆ FUN AWƆN ARA ILU NIKPA IBODIDI**



**SEMINAIRE NATIONAL SUR LE PROCESSUS ELECTORAL**
**(Elections législatives 1995)**

**COTONOU/CODIAM**
**26 - 27 JANVIER 1995**

HRE/CPR/(3)S/6

18921

INSTITUT DES DROITS DE L'HOMME ET DE PROMOTION DE LA DEMOCRATIE

LA DEMOCRATIE AU QUOTIDIEN

Siège : CODIAM à COTONOU (Bénin)
BP : 08-1120 COTONOU
Tél. : (229) 30-27-06 — Fax : (229) 30-27-07

# L'EDUCATION DES POPULATIONS EN MATIERE DE VOTE

## 3

Version Yòrùbá

*Eré akónilógbón kpɛlu ɛ̀rɔ amóhùnmáwòrán lori*

# EKƆ FUN AWƆN ARA ILU NIKPA IBODIDI

LIBRARY - BIBLIOTHEQUE
OHCHR

Ɛniti o da ere yii sinu
èdè yòrùbá ni Ɔlàdoshù SHAALA

HRE/CPR/(3)S/C

*Cette plaquette a été réalisée avec l'assistance financière de la Commission Internationale de Juristes (C.I.J.)*

*Kpὲlú àbáshekpɔ̀ C.I.J.*

# ƆRƆ ISHIWAJU

Ni abule kan diɛ ni o ku ki a fi kpari ìkéde eto ibiodidi kpɛlu gbogbo awɔn ohun ti ishɛ yìí mudani. Awɔn ara ilu ko tun ni isimi mɔ. Ɔjɔ gbogbo ni wɔn ma ngba alejo awɔn ti wɔn nwa oyè pkɛlu àròyé wɔn. O tilɛ wa rɛ awɔn ará ilu wɔnyi. Gbogbo awɔn ti wɔn nwa oyè nsɔ wikpé ki awɔn ara ilu dibo fun awɔn laishe alaye gɛgɛ bi ibodidi naa yio ti she lɔ gba fun wɔn. Ɔrɔ yìí wa kɔja awɔn agbɛ ti wɔn wa kpinnu wikpe awɔn yio lɔɔ ba akɔwe abule wɔn kan ti o kuro ni ilu nla lati le fi gbɔ gɛgɛ bi eto ibo yi o ti she lɔ si ni ɛnu rɛ.

Eleyi si she alaye fun wɔn ni ɛkunrɛrɛ (*kpɛlu awɔn aworan ti o yɛ*). Gbogbo ohun ti o nsɔ ni wɔn nri. Awɔn ara ilu si dukpɛ gidigidi ni ɔwɔ rɛ ki wɔn to tuka.

O wa di ɔjɔ ibo :

Ikɔ̀ ti ijɔba filelɛ fun abɛwo awɔn ibudo ibodidi de si ibudo kan, o si ri kpe gbogbo nkan nlɔ ni deede. Imurasilɛ fun ibo ti dɔgba.

Awɔn ara ilu ndibo (*aworan*) kpɛlu eto ti o yɛ. Ni ɛhin eeni, awɔn alabɛwo mojuto abɔ ibo yìí, wɔn duro ni ibi ti igbimɔ oludari ibo nka awɔn iwe ibo, wɔn si fun abɔ ni oju awɔn ti wɔn dibo. Ni igba ti abɔ naa kpari, ikɔ̀ kuro ni ibudo yìí kpɛlu inudidun o wa nduro de abɔ awɔn ibudo ti o ku.

## *ETO ERE*

**Ere kinni :**

A wà ni idi ɛro omi (pɔnpi) abule ti o si jinna diɛ si aarin ilu. A ri awɔn obinrin ti wɔn nlɔ ti wɔn nbɔ lati kpɔn omi rere. Ni ibɛ naa awɔn obinrin miran nfɔshɔ, awɔn miran nfɔ awo, ni asiko yìí kannaa awɔn ɔmɔde nshere. Ibɛ ni ɔrɔ kan bɛrɛ laarin awɔn obinrin meji (*Awawu* ati *Ajɔkɛ*) ti wɔn nfɔshɔ.

**Awawu** : Mo ni idaniloju wikpe abule wa ko gba awɔn alejo bayi ri. Ninu oshu meji ikɛhin yìí, bɛrɛ lati ɔjɔ aje de ɔjɔ aiku, awɔn eniyan lɔ́wɔ̌lɔ́wɔ̌ ni wɔn nlɔ ti wɔn si nbɔ, wɔn nkpébírí, wɔn nkpébìrì kpɛlu awɔn ara ilu wa naa.

**Ajɔkɛ** : Awawu! Ɛjɔ rɛ tɔ, o ri wɔn gan-an ni. Ni igba miran a tilɛ ma ngba ɔ̀wɔ́ ɔ̀tɔ̀ɔ̀tɔ̀ mɛta tabi mɛrin ni ɔjɔ kannaa. Ohun ti ko tilɛ wa ye mi ni wikpe mo gbɔ kpe olu ilu nla kannaa ni gbogbo wɔn nkuro. Mo wa nbi ara mi leere wikpe she wɔn ko le kpɛnukpɔ fi yan ɔ̀wɔ́ kanshosho ti wɔn yio fi ranshɛ kpe ki o wa sɔrɔ fun wa lɛɛkan naa ki o kpari ni. Ti mo ba ni àwa, awɔn baale wa ni mo nbawi, nitori kpe awɔn ni awɔn alejo wɔnyɛn ma nfamɔra, awɔn ni wɔn ma nsɔrɔ fun ti wɔn ba de.

**Awawu** : Mo tilɛ nbeere awɔn ohun ti wɔn nwa ni ɔdɔ wa to bɛɛ ti wɔn fi nwa titi de awɔn abule wa. Wɔn ko tun jɛ ki awɔn baale wa lɔɔ shishɛ oko wɔn mɔ.

**Ajɔkɛ́** : *(Rɛ́rĭn wúyɛ́)*
Awawu, alairidi nkan niɔ, ìkéde ibodidi ni. Ni aarin ɔsɛ melokan a o yan awɔn ɔga tuntun miran! Ibodidi ni a si gbɔdɔ fi yan wɔn. Wɔn nwa si ɔdɔ wa lati wa sɔ wikpe ki a dibo fun awɔn ni.

*(O nsɔrɔ kɛ́lɛ́kɛ́lɛ́ sii leti)*

Ara mi, ɔrɔ naa shòro o! Mo gbɔ wikpe kpɛlu owó ni wɔn ma nwa wɔn si nfun awɔn baale wa. Dɛkun! mo nbɛ ɔ, ma she bi baale rɛ jaye o. Ki o má she itori eeni fi beere owo kpukpɔ ni ɔdɔ rɛ.

**Awawu** : She ɔrɔ ibodidi ko kan awa ni? Ajɔkɛ, njɛ ti wɔn ba beere wikpe ki a dibo nkɔ, elo ni a o beere wikpe ki wɔn san fun wa?

**Ajɔkɛ** : Ɔrɔ wɔn ko ye emi naa daradara! Mo gbɔ ni ɛɛkan ri ni igba ti ɔkan ninu awɔn eniyan naa nsɔrɔ kpɛlu baale mi Ɔla wikpe gbogbo eniyan ni o nilati dibo. O tilɛ beere ni ɔdɔ Ɔla wikpe ki o sɔ ɛniti mo gbɔdɔ dibo fún fún mi.



*Ɛyin ara mi, ɛ ma she jɛ ki, awɔn ti nwa oyè ashofin ilu fi owo ra ìfɛ̃ yin ni asiko ìbòdídí*

**Awawu** : Gbogbo a wɔn wahala wɔn naa tilɛ su mi. Ti gbogbo awɔn eleeni ba jɔga tani wɔn yi o maa kpashɛ fun. Ati kpe njɛ ni asiko yìí nikan ni o yɛ ki wɔn wá wò wá?

**Ajɔkɛ** : Gbɔ ɔrɔ ti Awawu nsɔ.
Otitɔ ni gbogbo iyɛn. Shugbɔn o yɛ ki a wadi ɔrɔ naa ni awari. Bi a ba fɔshɔ tan ti mo ba dele ng o bi, Ɔla.Ti ko ba tilɛ fɛ fun mi ninu owo ti o gba, o sa yɛ ki o she alaye ohun ti o nshɛlɛ ni abule yìí fun mi.

**Awawu** : Ohun ti o yɛ ki a she niyɛn nitootɔ. Emi naa ng ó tan jaye ti mo ba dele. Ng o bii wikpe ki o she alaye awɔn ohun ti ibo yìí le yikpada ni abɛ́lé wa fun mi.

**Ajɔkɛ** : Igba ti a ti shetan, jɛ ki a maa lɔ ni ɛɛkannaa. Awa naa ni ɛtɔ lati wadi ɔrɔ yìí ki o le fi ye wa ni àyékpé.

*(Ajɔkɛ ati Awawu gbe basia awɔn ashɔ ti wɔn fɔ sori. A ri wɔn ti wɔn nwɔ abule wɔn lɔ)*

Jaye, Ɔla kpɛlu Kɛhinde ntayo ni abɛ igi nla kan ti o jɛ ibi ti awɔn ara abule ma saaba she ikpade. Ni asiko ti awɔn obinrin wɔnyi nkɔja ni iwaju wɔn, wɔn ki ara wɔn, Kɛhinde bɛrɛ si ba wɔn sɔrɔ, o nba wɔn dá àkpárá.

**Kɛhinde** : Héè! Ɛyin arɛwa obinrin! O jɔ wikpe o rɛ yin diɛ. O wa dabi ɛnikpe rírí ti ɛ ri awɔn baale yin ni ibi ko dunmɔ yin, ko tɛ yin lɔrun. Tabi ɔran kan ndun yin lɔkan ni?

*(A ri kpe Awawu ati Ajɔkɛ nshe ɔkan meji, wɔn ko mɔ ohun ti wɔn yi o she gan-an . Ɛnikan ninu wɔn nsɔ fun ɛnikeji rɛ wikpe ki o beere ɔrɔ naa)*

**Kɛhinde** : Mo rii nitootɔ wikpe nkan nbɛ ni ɔkan yin ti ɛ fɛ sɔ.

*(O nba awɔn ɛlɛgbɛ rɛ sɔrɔ)*

Héé! Ɛ gbɔ o,

inu awɔn iyawo wa ko dun o! O yɛ ki a tete bi wɔn ni ohun ti o ndun wɔn lɔkan; ti ko ba jɛ bɛɛ ti ɛ ba dele ɛ ò ni ri amala gbigbona jɛ. Ti o ba jɛ temi ni ko si ishoro yɛn fun mi. Nitori ibi ti mo ba ri ounjɛ ni mo njɛ.

*(Gbogbo wɔn busɛrin. Meji ninu awɔn ɔkunrin dide, wɔn sunmɔ awɔn obinrin. Wɔn fi Jaye silɛ. Bɛɛ si ni oun lo jɛ ɔ̀ta gidi ninu ayo ti wɔn nta lɔwɔ.*

**Ɔla** : Njɛ nitootɔ ni nkan nbɛ ni ɔkan yin ti ɛ fɛ sɔ? Iwɔ ni ti ɛ Ajɔkɛ, she mo sɔ fun ɔ wikpe mo nfɛ iyawo keji ni?

*(Awɔn obinrin wɔnyi sa nshe akɔ naa ni Jaye naa lɔɔ ba wɔn)*

**Jaye** : Ɛ gbɔ! Ti wɔn ko ba fɛ sɔrɔ, ɛ fi wɔn silɛ ki a maa ba ayò wa lɔ. Nitori kpe ɛnikan ninu awa ti nbɛ nibi ko gbe iná rù.

**Ajɔkɛ** : Kìí she bɛɛ, ɛ ma she binu. Awɔn nkan lo nshɛ ni abule wa lati bi igba melokan ti awɔn nkan naa kó si ye wa.

**Awawu** : *(O ri kpe oun ni agbara ati sɔrɔ nisisiyi)*
Bɛɛni, nitootɔ. Alɔ ati abɔ awɔn ɛgbɛ politiki lati bi igba melokan ko ye wa si. Ɔrɔ ibodidi, ibodidi ni igba gbogbo.

*(Kɛhinde busɛrin nla)*

**Kɛhinde** : Ɛyin alairidi nkan wɔnyi, ɛ ro wikpe awɔn baale yin naa ridi nkan ni?

*(Ɔrɔ yìí bi Jaye ninu gidigidi, o ri kpe Kɛhinde rɛ oun kpalɛ ni iwaju iyawo ti oun)*

**Jaye** : Kɛhinde, o ò le sɔ bɛ́ɛ̀. Emi ti mɔ wikpe ni igba ti mo ti gbɔ wikpe gbogbo

eniyan ni yio dibo, ng o de si ibi ibo naa dandan. Ti mo ba dibo temi tan, ng o dibo ni oruko iyawo mi, ni oruko aburo mi okunrin ati ni oruko gbogbo awon omo mi.

*(Kɛhinde tun busɛrin nla bi ti ɛɛkan)*

**Ɔlá** : O ò ! Jaye ohun ti wɔn sɔ kɔ niyɛn. Wɔn sɔ wikpe ɛnikɔɔkan yi o lɔɔ dibo ni orukɔ ara rɛ fun ɛniti ó fɛ́.

**Jaye** : Bɛɛni nitootɔ. Shugbɔn iyawo mi ni Awawu mo si san ɛru rɛ. Nitori bɛɛ ibi ti mo gbe ɛsɛ si ni oun naa gbɔdɔ gbe tiɛ si.

**Kɛhinde** : She o fɛ sɔ wikpe o she dandan ki ɔga ile orisha tabi ɔga ìjɔ kan gbɔdɔ dibo fun awɔn ɔmɔ ɛhin rɛ ni?

Kìí she bɛɛ, ɔrɛ mi ɔ̀wɔn. Ti awɔn eniyan ba nsɔrɔ, ɛ maa kɛti daradara lati fi gbɔ ohun ti wɔn nsɔ. Ɔga agbegbe (mɛ̀ɛ́ɛ̀) she alaye fun wa wikpe ɛnikɔɔkan ni o nilati lɔɔ fi orukɔ ara rɛ dibo fun ɛniti o wùú. Iyawo le dibo fun aburo ki baale dibo fun ɛgbɔn ɔmɔ iya ati ɔmɔ baba kannaa. Ɛnikan ko nilati kɔ fun ɛnikeji rɛ.

**Awawu** : She iyɛn jasi kpe awa obinrin naa a o lɔɔ dibo ni?

**Kɛhinde** : Gan-an bayi. Gbogbo awɔn ti wɔn ni o kere titi ɔdun mejidinlogun ibaa jɛ ɔkunrin, ibaa jɛ obinrin gbɔdɔ dibo.

**Jaye** : Nitootɔ emi ko lɔ si ile iwe gɛgɛ bi iwɔ, shugbɔn mo ni ɔgbɔn ati òye. Ki ɛ sì má she ba abule yìí jɛ.

**Kɛhinde** : Ng ò wikpe o jɛ òkpè. Eniyan le ma tete mɔ nkan shugbɔn ti ɛniti o ba ni ìmɔ̀ nshe alaye rɛ fun un, o yɛ ki o yee, kio si ma she gbagbe mɔ.

**Ajɔkɛ** : *(Nsɔrɔ fun Awawu)*
Inu mi ko dun. Ti ɔrɔ yìí ba di ija awa ni a o jɛ ɛniti o da a silɛ.

**Awawu** : *(ó bojujɛ diɛ kpɛlu ibinu)*
Fi wɔn silɛ ki wɔn maa sɔɔ́, awɔn ni wɔn mɔ ohun ti wɔn nri ninu rɛ.

*(Ni asiko ti wɔn nsɔrɔ yìí, ɔkɔ ayɔkɛlɛ kan yɔ ni ɔkankan, o si jɛ ti ɔga awɔn dotoo kan ti o jɛ ɔmɔbibi abule naa. O wa bɛ awɔn òbí rɛ wò ni ɔjɔ isimi.*

**Ɔlá** : Ɛ gbɔ o ɛyin ɔrɛ mi, ko yɛ ki ɛ maa ba ara yin jà. Ɛnikan ti de si abule wa nisisiyi ti o si mɔ nikpa ɔrɔ ibodidi ju gbogbo awa ti nbɛ ni ibi lɔ.O si tun jɛ ɔmɔ abule wa. Eleeni le laja fun wa. Ko le kpurɔ fun wa.

**Jaye** : Otitɔ ni, ɛ jɛ ki a lɔɔ wòó. Oun ni o tilɛ gba ibi kɔja laikpe kpɛlu ɔkɔ̀ ayɔkɛlɛ yɛn.

**Ajɔkɛ** : Njɛ awa naa le ba yin lɔ?

**Awon ɔkunrin mɛtɛɛta** : gan-an bayi, ɛ le ba wa lɔ.

*(A ri gbogbo wɔn ti wɔn mu ɔna ile dotoo agba pkɔ̀n kpɛlu ɔrɔ ti wɔn ti nsɔ bɔ lɛnu. Igba ti wɔn de si ɛnu-ɔna, awɔn obinrin gbe ɛru wɔn silɛ . Jaye ni ɛniti o kɔkɔ wɔle, awɔn to ku wa tɛle e. Dooto si gba wɔn ni ìta ti nbɛ ninu ile rɛ. Iyàlɛ́nu ni wíwá ti wɔn wa si ɔdɔ rɛ jɛ fun un. O si tun wa jɛ idunnu fun un ni idakeji)*

**Dotoo agba** : Ɛ kaabɔ o ɛyin ara mi lɔkunrin ati lobinrin. Mo de ko kpɛ. She ko si nkan ti mo fi ri yin bayi o.

**Jaye** : Irɔ o, ɛgbɔn, ko si aidara. Ɔrɛ wa Kɛhinde ni ko ridi nkan o si fɛ ko gbogbo wa sinu ɔkɔ̀ airidi nkan rɛ. O nkpe ara rɛ ni ɔ̀mɔ̀wé bɛɛ si ni iwe mɛfa kpere ni o kà.

**Kɛhinde** : Dotoo, gbogbo ohun ti a nfɛ ni wikpe ki ɛ she alaye kpikpe fun wa lori gbogbo awɔn ohun ti o jɛmɔ́ ibodidi.

**Ɔlá** : Ɔkpɔ eniyan lo nwa si ɔdɔ wa ni ibi ti wɔn si nsɔ wikpe ki a dibo fun awɔn, bɛɛ si ni ɔrɔ ibo yìí ko ye wa si daradara. A nfɛ alaye kpikpe lori rɛ ki a le fi yan awɔn ɔga wa ti a o dibo fun.

**Dotoo** : Ɛyin ara mi ɔwɔn lɔkunrin ati lobinrin, mo gba fun yin, ìrìn yin dara ju.

Iwadi ti ɛ nshe dara, o yɛ ki ɛyin naa mɔ gɛgɛ bi ɔrɔ ibodidi yi o ti lɔ si nitootɔ.

Ki ng to fun yin ni esi awɔn ohun ti ɛ beerɛ, mo fɛ she atunshe kan ninu ɔrɔ ti ɛni-ɔ̀wɔ̀n mi Ɔla sɔ. Kìí si she wikpe oun nikan ni o ni èrò bɛɛ. Kpukpɔ ni aarin ɛyin ara mi ɔkunrin ro wikpe awɔn yio dibo lati fi yan awɔn ɔga ni. Irɔ, kìí she bɛɛ rara! Awɔn ɛniti a ma nyan kìí she ɔga wa. Ibaa jɛ ààrɛ ilu, ibaa jɛ ashofin ilu, ibaa jɛ ɔga adugbo tabi awɔn oshelu miran ashoju ilu ni wɔn jɛ; shugbɔn wɔn le de ori ijan oye tan ki wɔn maa kpe ara wɔn ni ɔga. - Oshelu ti a yan ni wɔn, agbɔrɔsɔ, iranshɛ gbogbo ilu ni wɔn jɛ.

*(Gbogbo awɔn alaye ti Dotoo she yìí lo ni aworan. A ngbɔ ohùn Dotoo ti o ki daradara ni kɔ̀rɔ̀ kan ; shugbɔn a ko ri oun naa)*

**Dotoo** : Ki lo njɛ ibodidi? Ibodidi jɛ ɔna kan ti ara ilu ngba fi sɔ gɛgɛ bi o ti yɛ

ki a she akoso awɔn ara ilu, awɔn dukia ilu, gɛgɛ bi awɔn ti wɔn nwa oyè gbɔdɔ tɔju awɔn ɔmɔ ilu, gɛgɛ bi wɔn gbɔdɔ she ishɛ wɔn ki ilu le fi ni irɔrun ti o yɛ.

Ɔna ibodidi ni ɔmɔ ilu ngba fi yan ɛniti o wù ú ki o jɛ alakoso awɔn gbogbo ohun ilu lɔna ti o wulo. O nfi ifɛ ara rɛ han nikpa lílɔ́wɔ́ ninu akoso awɔn ara ilu.

**Ɔla** : Iyɛn jasi kpe olukuluku ni o wa nsɔ ohun ti o wù ú, ohun ti o jɛ ifɛ ɔkan rɛ?

**Dotoo** : Bɛɛni. «Ti gbogbo ayé ni ibodidi jɛ, ɛ̀tɔ́ kannaa ni gbo eniyan ni nikpa ibodidi. Kɔ̀rɔ̀ si ni a ma ndibo kìí she gbangba. Ɛnikan ko nilati mɔ iwe ti ɛnikeji rɛ fi sinu akpo iwe... Awɔn ɛgbɛ politiki, awɔn ti wɔn nwa oye, awɔn oshelu ati awɔn adibo yo ku ko nilati mɔ iwe ibo ti ɛnikan gbe sinu akpo iwe ibo.

**Jaye** : Iyɛn jasi kpe iyawo mi nikan le lɔɔ dibo laima sɔ ɛniti o dibo fún fún mi?

**Dotoo** : Gan-an bayi: Ninu ibodidi ohùn iyawo rɛ dɔgba kpɛlu ti ɛ naa ni. Ɛnikɔɔkan si ni àyè lati fi dibo fun ɛniti ó wù ú.

**Awawu** : Njɛ gbogbo eniyan lo nilati dibo naa, awɔn ɔmɔde ati awɔn alaisan?

**Dotoo** : Bɛɛni, gbogbo awɔn ti wɔn ti ni o kere titi ɔdun mejidinlogun, ti wɔn si jɛ




*Ibodidí she kpataki.*
*O si gbɔdɔ tɛle ofin ti ijɔba filelɛ.*

ɔmɔ ilu rere ti ori wɔn ko dàrú le dibo, bakannaa wɔn tun le fi orukɔ silɛ wikpe awɔn naa nwa ati joye ti o ba she wikpe wɔn ko shɛwɔn ri fun oshu mɛta tabi ju bɛɛ lɔ nikpa ki wɔn huwa kuwa, iwa akpaniyan, ki wɔn jale, ki wɔn fi ikpa faraya, ki wɔn gba àgbàjìgì tabi ki wɔn da ɛniti o fi ɔkàn tɛ́ wɔn.

**Ajɔkɛ** : Bawo ni awɔn arugbo, awɔn alaisan, awɔn aboyun ti inu nja ti wɔn ko le lɔ si ibi ibodidi yi o she?

**Dotoo** : Ɔna ti awɔn ti wɔn ko le lɔ si ibi ibodidi yi o gba fi dibo nbɛ. Ofin ti sheto gbogbo rɛ silɛ. Ti o ba jɛ wikpe ɔmɔ ilu ti ara rɛ mɔ kan ko raye lɔ si ibi ibodidi, o le yan ɛniti o wù ú lati lɔɔ dibo ni orunkɔ rɛ kpɛlu iwe ibo rɛ. Yi o fun eleeni ni iwe ɛri kpe bɛɛni, oun ni oun ran an nishɛ nitootɔ. Ɔga adugbo tabi ajɛlɛ yi o si ti tɔwɔbɔ iwe ɛri yìí ki o to wulo nibi ibo. Ɛniti a si ran ni ishɛ naa nilati jɛ ɔmɔ ilu rere ti ara rɛ mɔ. Ori iwe ti a kɔ orukɔ awɔn adibo si kannaa ni orukɔ ɛniti a ran ni ishɛ ati orukɔ ɛniti o ranshɛ gbɔdɔ wa.

*(Ni asiko ti Dotoo nsɔrɔ, oludari ere yìí yio maa fi aworan awɔn arugbo , awɔn alaisan ati awɔn aboyun han kpɛlu ɛrɔ amóhùnmáwòrán)*

**Jaye** : Tulaasi ni ibodidi jɛ fun baale, iyawo ati awɔn ɔmɔ ni? Ɛ tilɛ jɛ ki ng bi yin, kinni ohun ti wɔn yi o she fun mi ti ng kò ba lɔɔ dibo.

**Dotoo** : Ɛnikan ko ni she nkankan fun ɔ ti o kò ba lɔɔ dibo, shugbɔn o yɛ ki o lɔɔ dibo ni aarin agogo meje owurɔ ati agogo marun irɔlɛ kpɛlu ifɛ rere, idunnu laisi wahala kan. Nitori kpe ibodidi ni awɔn ɔmɔ ilu fi ma nyan awɔn ashoju wɔn ti wɔn si fi ma nsɔ gɛgɛ bi a nilati maa dari ilu lɔna ti o tɔ, ɔna ti yi o fun ilu ni irɔrun. Fun eyi, ti ɔkpɔ eniyan ko ba jade lati lɔɔ dibo, awɔn amutikpara ati awɔn olè melokan le yan amutikpara tabi ole ɛlɛgbɛ wɔn kan gɛgɛ bi ashoju ilu tabi agbɔrɔsɔ wɔn. Ti o ba si wa di kpe ɔrɔ naa lɔ bɛɛ, awɔn ti wɔn ko lɔ sibi ibo ko ni ashɛ lati kɔ agbɔrɔsɔ ti wɔn yan fun wɔn. Wɔn yio kan faramɔɔ bɛɛni.

**Ɔla** : Mo bɛrɛ si mɔ ohun ti o njɛ ibo ati ohun ti o fa ti gbogbo eniyan fi gbɔdɔ dibo. Dotoo, amà awɔn ishoro mi ko iti tan.

**Dotoo** : NI suuru diɛ Ɔla, ng ò gbagbe alaye ti o beere lori eto ibodidi.

Nitootɔ, ìgbésɛ̀ kpukpɔ ni nbɛ ki a to de ori ibodidi.

Ti asiko ba to awɔn ti wɔn nbɛ lori eto ibodidi yi o shí iwe iforukɔ silɛ fun



*Awɔn alaisan, awɔn arugbo, awɔn aboyun, ani gbogbo awɔn ti wɔn ko raye fi lɔɔ dibo le yan ɛniti o wu wɔn kpe ki o dibo ni orukɔ awɔn kpɛlu iwe ɛrí wikpe awɔn ni wɔn yan eleeni nitootɔ.*

ibodidi, gɛgɛ bi mo ti she sɔɔ ni aikpɛ yìí, ɔmɔ ilu ti o ni, o kere titi ɔdun mejidinlogun yio mu iwe ifinihan rɛ dani lati lɔɔ fi orukɔ silɛ ni adugbo rɛ fun ibodidi. Ti ko ba si ni iwe ifinihan yìí o le gbani iwe ifinihan ti a ma nmulɔ ilu okeere tabi ti a ma fi nwɔ ɔkɔ̀ òkè, ti ko ba si ni eeni naa o le mu iwe ɔjɔ ibi tabi iwe ɛri mo jɛ awakɔ̀, tabi iwe ɛri mo jɛ ɔlɔkpa, tabi iwe ti awɔn onisimi afɛhinti fi ma ngbowo, tabi gbogbo iwe miran ti o le fi ɛniti o fɛ fi orukɔ silɛ fun ibodidi han dani.

Ti ɛ ko ba wa ni ɔkankan ninu gbogbo awɔn iwe ti a ka wɔnyɛn, igbimɔ awɔn àgbà abule tabi ti adugbo ilu nla le jɛri kpe ɔmɔbibi ilu Benɛɛ ni ɛ jɛ́, ɛ le nikpin ninu ibodidi.

*(Oludari eré yi o fi aworan iwe ibo kan han ni nla kpɛlu ɛrɔ amohunmaworan)*

**Jaye :** Eyi jasi kpe ti mo ba ng gbe ni ibí ng ò le lɔɔ dibo ni adugbo miran niyɛn.

**Dotoo :** Bɛɛni Jaye, ki eniyan gba iwe ibo rɛ ni adugbo ti o ngbe ni irɔrun ju lɔ. Ibi ti eniyan si gba iwe ibo ni o nilati dibo, kìí she ibomiran.

O si tun she kpataki ki ng fi ye yin

wikpe ìjèbi nla òfin ma nfun ɛniti o kpurɔ orukɔ mɔ ara rɛ ni asiko ti o ngba iwe ti yi o fi dibo. Kàkà ki o kɔ orukɔ ti o njɛ nitootɔ ti o ba lɔɔ kɔ orukɔ miran tabi ki o fi orukɔ silɛ ni ɔna meji tabi ju bɛɛ lɔ.

Yi o shɛwɔn yi o si tun sanwo bakannaa. Ijɛbi kannaa ni ofin ma nfun awɔn ti wɔn nmu ohun-ija dani lɔ si ibi ibo. Bi a ba ni ohun-ija kìí she ibɔn dandan. O le jɛ ɔ̀bɛ, ààké, àdá, ɔ̀kpá nla, shɔ̀kùbɛ́lɛ́ tabi ohun-ija miran.

Ɛ gbɔdɔ túdǐ ɛniti nfun yin ni awó tabi ti nshe ileri wikpe oun yio fun yin ni nkan ki ɛ le fi dibo fun un tabi fun ará rɛ̀ kan, nitori kpe ofin ti kɔ̀ɔ́.

**Kɛhinde** : Dotoo, ti ng kò ba beere ki ó tó fun mi nkɔ?

**Dotoo** : Ti o ba gbàá, iwɔ ati ɛniti o fun ɔ gbogbo yin ni ɛ o shɛwɔn to ɔdun marun ti ɛ o si tun san owo ɛ̀bi ti o le to miliɔn kan bɛɛ.

**Kɛhinde** : Dotoo, mo dukpɛ kpukpɔ ni ɔwɔ yin. Adura ti o ku ti ng o maa gba ni wikpe ki awɔn ɔrɛ mi ma she ishekushe ni ɔjɔ ibo. Ti o ba jɛ temi ni, mo ti nkanju ju kpe ki ɔjɔ naa tete wá. Nisisiyi, Dotoo, a o maa lɔ.Lɛɛkan si, ɛ shee kpukpɔ.

**Dotoo** : Irɔ, emi ni mo gbɔdɔ dukpɛ ni ɔwɔ yin, nitori kpe ɔkpɛ́lɔkpɛ́ yin ni mo le fi shishɛ mi bi o ti yɛ. Ohun ti o tɔ́ ki ɔmɔ ilu ti ɔrɔ ibodidi ye diɛ ju awɔn to ku lɔ she niyɛn. Eyi to ku wa di ɔwɔ yin. Ɛyin ni ɛ o ran awɔn ara wa ti ɔrɔ yìí ko iti ye lɔwɔ ki o le fi ye wɔn.

*(Lori ɔrɔ yìí ni gbogbo wɔn tuka kpɛlu idunnu)*

## Ere keji

*(O di ɔjɔ ibo. Ni owurɔ a ri aye ibodidi ninu ile iwe kan. Awɔn oludari ibo joko kpɛlu awɔn ashoju ɛgbɛ politiki. Awɔn ti yi o dibo naa ti tò. Ikɔ̀ kan ti o nshe abɛwo awɔn aye ibodidi de lati wa shí ibo)*

**Alága ikɔ̀** : *Nbá awɔn adibo ti wɔn ti de ni ibi ibo ati awɔn oludari ibo sɔrɔ.*
Mo dukpɛ kpukpo ni ɔwɔ yin fun dide ti ɛ tete de lati wa she ishɛ ti ɔmɔ ilu rere gbɔdɔ she.

Emi ati awɔn ti wɔn tɛle mi ni ijɔba yan lati mojuto ibodidi ki gbogbo nkan le fi lɔ ni deede. A o gba gbogbo ibi ti awɔn eniyan ndibo, a o maa gba wɔn ni imɔran ti o yɛ ki a to lɔ si ibomiran. Gbogbo ishɛ ti o yɛ ni a ti she ki ibo yìí le fi jasi



*A gbɔ́dɔ̀ ti àkpóti ìbò ni àtikpa kpɛlu kɔ̀kɔ́rɔ́ rere.*

rere. Ɛyin ɔrɛ mi, mo nbɛ yin wikpe ki ɛ ni suuru fun ishɛju melokan ɛ fun wa ni asiko diɛ ki a fi wo bi gbogbo awɔn eelo ibo ti dɔgba ki ɛ le fi dibo yin laisi wahala. Bi o ti wu ki o ri, ibo yi o bɛrɛ ni agogo ti ijɔba fun.

Alaga bɛrɛ si yɛ awɔn eelo ibo melokan wo.

*(Oludari ere yi o maa fi eelo kɔɔkan han ni nla kpɛlu ɛrɔ amohunmaworan)*

**Alaga** : Njɛ gbogbo awɔn ɛgbɛ politiki ni ashoju wɔn ni ibi?

**Ɔwɔ awɔn eniyan kan dáhùn** : A wà ní ibí

*(Oludari ere yi o fi wɔn han ni nla kpɛlu ɛrɔ amohunmaworan)*

**Alaga** : She gbogbo wa ri nisisiyi daju kpe ɛgbɛ politiki kɔɔkan ni ɔkpɔ iwe ibo rɛ ni ibi bi o ti yɛ.

**Awɔn oludari ibo** : Bɛɛni!

*(Oludari ere yi o fi iwe ibo ɛgbɛ politiki kɔɔkan han ni nla kpɛlu ɛrɔ amohunmaworan)*



*Ki a to gba ɔ laye lati lɔɔ dibo, o gbɔdɔ ti f i o rukɔ rɛ silɛ ninu iwe ti a gba orukɔ awɔn ti yi o dibo si.*

**Alaga** : Nisisiyi a o wa wo bi ile kekere ti a kɔ́ fun awɔn adibo, ninu eyi ti wɔn yi o maa sakpamɔ fi dibo ti dɔgba bi a ti she nfɛ, nitori kpe ɛlomiran ko gbɔdɔ ri ɛniti o wà ninu rɛ ti o ngbe iwe ibo sinu akpo iwe.

*(Oludari ere yi o fi ile kpókótó naa han ni nla kpɛlu ɛrɔ amohunmaworan)*

**Alagba** : *(Nsɔrɔ fun awɔn adibo)*
O da mi loju kpe ɛ mɔ wikpe ishɛ kpataki kan ni ɛ fɛ she fun ilu yin ni oni, nitori rɛ ni ɛ fi tete de si ibi ni owurɔ yìí. Sibɛ sibɛ mo ntɔrɔ ni ɔdɔ yin wikpe ki ɛ gba mi laye diɛ lati fi she alaye awɔn ohun ti ɛ o she ni ibi fun yin ni ɛɛkan sii. Gɛgɛ bi ɛ ti she to kpɛlu irɛlɛ yìí ni ɛnikɔɔkan yin yi o maa fi gba iwaju awɔn ti wɔn ndari ibo laisharoye, laiti ara yin. Ishɛ awɔn oludari ibo naa ni wikpe ki wɔn maa yɛ iwe ti ɛ gbà ni asiko ti ɛ fi orukɔ silɛ wò, ki wɔn si wa wo bi orukɔ yin nbɛ ninu iwe nitootɔ. Ti ɛ ba dibo bushe, ɛ o tun gba iwaju wɔn lati tɔwɔbɔwe, nitori kpe ɛnikan naa ko gbɔdɔ dibo ni ɛɛmeji.

*(Adibo kan yio she gbogbo awɔn ishɛ wɔnyi ti a o maa fihan kpɛlu ɛrɔ amohunmaworan. A o maa gbɔ ohùn gbígbɛdɛ̀ alaga ni*

*kɔ̀rɔ̀. A ko ni ri oun naa)*

Adibo kɔɔkan yi o mu iwe ibo kɔɔkan ninu gbogbo awɔn iwe ibo ti nbɛ lo ri tabuu yi o wa mu akpo iwe kan. Yi o bɔsi inu ile kekere kan ti a kpesesilɛ fun ibo. Yio gbe iwe ɛniti o wùú sinu akpo iwe naa.

Shugbɔn ɛyin ɔrɛ mi, ɛ farabalɛ. Ɛ shɔra yin. Ki ɛ ma she gbe iwe ibo ɔtɔɔtɔ meji sinu akpo iwe kannaa. Amì kan kò gbɔdɔ si ni ara iwe ati ni ara akpo iwe ibo. Ɛ ko gbɔdɔ lo akpo iwe mi̥ran yatɔ si eyi ti awɔn oludari ibo gbe fun yin. Ti ɛ ko ba tɛle awɔn imɔran melokan wɔnyi ibo ti ɛ di le jasi asan. awɔn oludari ibo le kɔ̀ɔ́ ni asiko ti wɔn yio ka awɔn iwe ibo ti a gbe sinu àgbá.

Ti ɛ ba fi iwe ibo sinu akpo iwe tan ɛ o kpada wa ni iwaju awɔn oludari ibo lati wa fi ɔwɔ́ ara yin sɔ akpo iwe yìí sinu àgbá ibo.

Ni iwɔn igba ti o jɛ wikpe ɛyin ni ɛni akɔkɔ ti o dibo ti o si tun jɛ wikpe awɔn ashoju awɔn ɛniti wɔn nwa oye ti nbɛ ni ibi ibo, a gbɔdɔ ni idaniloju kpe nkankan ko ti si ninu àgbá ki a to bɛrɛ ibodidi.

*(A o fi inu àgbá han ni nla kpɛlu ɛrɔ amohunmaworan)*

Ni ɛhin iyɛn, a o wa se agba ibo yìí a o tìí ni atikpa kpɛlu kɔ́kɔ́rɔ́ ti o shɔ̀wɔ́n.



*Gbogbo eniyan ɔrɔ ìbòdìdí kan : Awon obinrin naa nbɛ ninu rɛ.*

*(A o wa fi àgbá ti a tì ni atikpa han kpɛlu ɛrɔ amohunmaworan)*

Njɛ, ɛyin ɔrɛ mi, ohun ti o ku fun yin nisisiyi ni wikpe ki ɛ she ishɛ ti ɔmɔ ilu rere gbɔdɔ she, iyɛn ni ibodidi.

*(A o fi awɔn adibo melokan ti wɔn ndibo han kpɛlu ɛrɔ amohunmaworan)*

Awɔn ti wɔn fɛ wà ni ibi ti a o ka awɔn iwe ibo ni ìrɔ̀lɛ́ yìí le kpada wá si ibi ni agogo marun gérégé.

*(Nisisiyi a de sinu yara ile ishɛ ɔga adugbo kan ( Mɛ̀ɛ̀rí ì) ti o ni àyè daradara ati atɛgun rere.*
*A nwo abɔ ibo kan.*
- *Ayɛwo akpoti tí a tì ni atikpa*
- *Kika awɔn ti wɔn dibo lati fi mɔ i yatɔ ti nbɛ laarin wɔn kpɛlu awɔn ti wɔn fi orukɔ silɛ fun ibodidi.*
- *Kika iwe ibo ɛnikɔɔkan ti o fɛ joye ashofin ilu.*

*Lati kɔ̀rɔ̀, ohùn gbígbɛdɛ̀ kan ti a ko ri olóhùn nshe alaye lori ibo, alaye yìí lo mu ki awɔn aworan ti a nri rɔrun lati mɔ.*
*Ni ɛɛkɔɔkan ɛrɔ ma nfi Ɔla, Kɛhinde ati Jaye ti wɔn nfi tɔkan tɔkan wo eto ibo yii han.*
*A fun abɔ ibo ti ibudo yìí.*



*Gbogbo awɔn ɛniti wɔn fɛ́ le duro ni ibi ti a o ka awɔn iwe ibo ti a ba dibo bùshe.*

*Kɛhinde , Ɔla ati Jaye kuro nibɛ. Wɔn de sinu ile ɔti kekere kan)*

**Kɛhinde** : Háà! Ɛyin ara mi, ohun ti a nkpe ni ibo rere niyɛn. Awɔn ti wɔn fɛ joye Sare kaakiri gbogbo awɔn abule sibɛ sibɛ ɛniti o wu ara abule kɔɔkan ni o dibo fun laisi wahala kankan.

**Jaye** : Iwɔ ti o nkpe ara rɛ ni "momɔ̀ɔ́tán" njɛ o ti mɔ gbogbo awɔn eto naa bɛɛ tɛlɛ?

**Ɔla** : Ɔrɔ eeni ti kɔja. Ohun kpataki ti o ku ki a she ni wikpe ki olukuluku mɔ lati isisiyi lɔ ohun ti o nilati she ni ɔjɔ ibodidi ati ni asiko ti a o ka awɔn iwe ibo ti a ba dibo tan.

**Jaye** : Ɛjɔ rɛ tɔ gan-an ni, o tun yɛ ki o ye wa wikpe ibodidi kìí she ìjà, kìí si she ogun gɛgɛ bi awɔn ɛgbɛ politiki ti wɔn ti nwa si ɔdɔ wa ni abule ti she nsɔ fun wa.

**Kɛhinde** : Ti o ba ti ye Jaye bɛɛ, njɛ ɔrɔ bushe, ohun ti o ku fun wa ni wikpe ki a maa mu ɔti wa lɔ, nitori kpe ɛniti oyè yìí tɔsi ni yio jɛɛ́.

*(Wɔn gbe kɔ́fù wɔn soke, wɔn mu ɔti, wɔn si wa dá orin kan ti wɔn shɛ fun ibodidi naa)*

***IKPARI***

## AWƆN OSHERE KPATAKI

1 - Awawu
2 - Ajɔkɛ
3 - Kɛhinde
4 - Ɔla
5 - Jaye
6 - Dòtóò àgbà
7 - Alagba

## AWƆN OHUN EELO IBO TI O YƐ

1 - Iwe ɛ̀rí adibo
2 - Iwe nla ninu eyi ti a kɔ orukɔ awɔn adibo sí
3 - Akpoti ibo ti a tì kpɛlu kɔ́kɔ́rɔ́
4 - Awɔn ohun eelo òùntɛ̀
5 - Ile àshírí ni ibi ti adibo nyan ɛniti ó wùú
6 - Iwe ibo (a o tɛ̀ɛ́)
7 - Akpo iwe
8 - Ɔkɔ̀ ayɔkɛlɛ
9 - Kɛkɛkpukpu
10 - Ɔkɔ̀ nla.

## AWƆN AYE TI A GBƆDƆ WA

1 - Ojúlé ishɛ ɔga agbegbe kan ni aarin ilu kutɔnu
2 - Ile ɛkɔ kan
3 - Odò kan
4 - Ile kan ti agboro inu rɛ fɛ̀
5 - Abɛ igi kan ni ibi ti awɔn eniyan ma nnaju.

## AWƆN EELO ISHƐ MELOKAN TI OLUDARI ERE GBƆDƆ WA SILƐ

**Aworan arugbo kan, ti alaisan kan, ti obinrin kan ti o nrɔbi (ti inu nja).**
**Ati awɔn aworan miran ti oludari ere ro wikpe o she kpatakiɛ.**

*Impression : Imprimerie Notre-Dame*
*BP : 105 • Tél : (229) 32-12-07 • Fax : (229) 32-11-19*
*N° d'impression 0093 - 03 - 1995*
*Dépôt Légal : 1er Trimestre 1995*
*Produit en République du Bénin*



OHCHR LIBRARY
7922